# A FI ẸMI MIMỌ́ WỌ AWỌN ARA EFESU

**Iṣe Awọn Apọsteli 19:1-20**

**ẸKỌ 338 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun awọn enia na, ti ẹniti Ọlọrun OLUWA iṣe" (Orin Dafidi 144:15).**

## Paulu Sọ nipa Ẹmi Mimọ́

Paulu Apọsteli bẹ Efesu wò nigba ti o n ti Kọrinti lọ si Jerusalẹmu ninu irin-ajo rẹ keji lati tan Ihinrere kalẹ. O ti waasu fun awọn Ju ninu sinagọgu wọn fun igba diẹ, wọn si gba ọ̀rọ iwaasu rẹ, wọn tilẹ fẹ ki o duro pẹ diẹ lọdọ wọn. Ṣugbọn oun kò le duro nigba naa, ṣugbọn ni akoko yii, ninu irin-ajo rẹ kẹta lati tan Ihinrere kalẹ, o wá si Efesu lati wà nibẹ fun iwọn igba diẹ.

Paulu ri awọn ọmọ-ẹyin kan ni Efesu awọn ẹni ti o gbagbọ́ tọkàntọkàn ti wọn si n tẹle gbogbo ẹ̀kọ́ ti wọn ti gbọ́, nitori naa o bi wọn leere bi wọn ti gbà Ẹmi Mimọ́. Wọn kò tilẹ loye ohun ti o n sọ rára. Wọn dahun pe, "Awa kò gbọ́ rara bi Ẹmi Mimọ́ kan wà."

## Ṣisẹ N Tẹle

Nigba ti eniyan bá ṣẹṣẹ ni igbala, inu rẹ yoo dùn pupọ to bẹẹ ti kò ni ranti fun iwọn igba diẹ pe ohun kan tun wà lati beere lọwọ Ọlọrun. Ṣugbọn bi o ba ṣe diẹ si i, oungbẹ kan yoo wọ ọkàn rẹ lati tubọ tẹ siwaju. Bi o ti n gbadura ti o si n fi ara rẹ rubọ fun Ọlọrun, ti o si gbagbọ́ lati ni isọdimimọ́, Ọlọrun yoo tun fi ayọ̀ kun ọkàn rẹ nipa fi fun un ni iriri miiran. Wo bi ọkàn rẹ yoo ti jẹ́ mimọ́ laulau! Wo bi alaafia yoo ti kun ọkàn rẹ pọ̀ tó! Ọlọrun ti fun un ni ifẹ! Nipa iriri yii a fun un ni agbára ti o tobi ju ti akọkọ lọ lati rọ̀ mọ́ igbagbọ́ ti Ọlọrun ti fi fun un, ati lati bori ẹ̀ṣẹ. A tu gbongbo ẹ̀ṣẹ kuro.

Ẹnikẹni ti o bá n fẹ ohun ti o dara jù lọ lọwọ Ọlọrun ni anfaani lati tẹ siwaju si i. Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ ki O to lọ pe ki wọn duro ni Jerusalẹmu titi wọn yoo fi gba ileri Baba, eyi ti i ṣe agbára Ẹmi Mimọ́. Jesu ti gbadura fun isọdimimọ́ wọn, O si ti mí Ẹmi Mimọ si wọn (Johannu 20:22), ṣugbọn wọn ni lati gba agbára Ẹmi Mimọ́. Ohun kan ti o tobi ju eyi lọ si tun wà fun wọn. "A o fi Ẹmi Mimọ́ baptisi nyin, ki iṣe ọjọ pupọ lati oni lọ" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:5).

## Agbara fun Isin

Iṣẹ pupọ ni o wà fun awọn ọmọlẹyin Jesu lati ṣe ni titan Ihinrere kalẹ. Wọn ni lati ni iranwọ lati Ọrun. Jesu wi pe "Ẹnyin ó gbà agbara, nigbati Ẹmi Mimọ́ ba bà le nyin: ẹ o si ma ṣe ẹlẹri mi ni Jerusalẹmu, ati ni gbogbo Judea, ati ni Samaria, ati titi de opin ilẹ aiye" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:8). Agbara yii ni olukuluku ọkàn ti n fẹ ṣiṣẹ fun Oluwa ni lati ni.

A ko gbà wa là lati joko ki a si maa jẹ igbadun alaafia ati irọra ati itunu. Ibukun Oluwa jẹ iyanu, O si n fẹ ki a layọ: ṣugbọn kò si ẹni ti o ni ayọ bi ti ẹni ti n ṣe iṣẹ-iranṣẹ fun awọn ẹlomiran. A fun wa ni ibukun ki a ba le jẹ ibukun fun ẹlomiran. Ileri Rẹ lati wà pẹlu wa jẹ ti awọn ti yoo jade fun Un. "Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède gbogbo, … ẹ si kiyesi i, emi wà pẹlu nyin nigbagbogbo, titi o fi de opin aiye" (Matteu 28:19, 20).

Eyi ni Paulu n sọrọ nipa rẹ fun awọn ara Efesu. Njẹ wọn ha ti ni iriri ologo yii ti yoo fun wọn ni agbára lati jẹ ẹlẹri ni gbogbo ayé? Wọn ha ti ni Olutunu nì ninu igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi Jesu ti ṣeleri? Wọn ko tilẹ mọ̀ rara pe wọn le ni irú ibukun nla bayi lati ọdọ Ọlọrun!

## Iribọmi

Paulu tun beere ibeere miiran. Bi awọn ara Efesu kò ba ti gbọ́ nipa Ẹmi Mimọ́, njẹ ilana wo ni wọn ha tẹle nigba ti a ri wọn bọ omi? Aṣẹ ti Jesu pa nipa iribọmi ni pe ki a ri wọn bọmi "li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ́" (Matteu 28:19). Bi a ba ti ri wọn bọmi li ọ̀na bayi wọn i ba ti mọ pe Ẹmi Mimọ́ wà.

Awọn ara Efesu dahun pe a baptisi wọn si baptismu ti Johannu. Diẹ kiun ni a mọ̀ nipa iribọmi ti Johannu; ṣugbọn a mọ̀ pe iṣẹ Johannu ni lati pese ọkàn awọn eniyan silẹ fun bibọ̀ Jesu. Ohun ti o n kede

ni pe: “Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀.” Ọpọlọpọ awọn eniyan ni o tọ̀ Johannu lọ lati gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀, awọn miiran tilẹ rò pe oun ni Messia. Ṣugbọn Johannu dahun pe: “Lõtọ li emi nfi omi baptisi nyin fun ironupiwada: ṣugbọn ẹnikan ti o pọ̀ju mi lọ mbọ̀ lẹhin mi, bàta ẹniti emi ko to gbé; on ni yio fi Ẹmi Mimọ́ ati iná baptisi nyin” (Matteu 3:11). Nitori naa iribọmi ti Johannu kò tó.

Nigba ti Jesu pari iṣẹ irapada ti O wa ṣe laye ti O si pada lọ si Ọrun, igba titun dé. Nigba ti awọn ọgọfa eniyan ni yara oke gba agbára Ẹmi Mimọ́ ni ọjọ kẹwaa lẹyin ti Jesu goke re Ọrun, ni igba ti Ẹmi Mimọ́ ti bẹrẹ̀.

**Fun awọn ti o Jinna rere**

Ki i ṣe iba awọn eniyan ti o gba agbára Ẹmi Mimọ́ ni ọjọ naa nikan ni gbigba agbára Ẹmi Mimọ́ pin si. A ti kọ́ ẹ̀kọ́ nipa awọn Keferi ti o gba agbára Ẹmi Mimọ́ ni ọdun diẹ lẹyin ọjọ Pẹntekọsti (Ẹkọ 290, 304). Ọdun kẹtalelogun lẹyin ọjọ Pẹntekọsti ni akoko ti Paulu lọ lati bẹ Efesu wò yii, awọn ọkunrin mejila ninu wọn ni o si gbà Ẹmi Mimọ́. Peteru Apọsteli ti wi pe: “Fun nyin ni ileri na, ati fun awọn ọmọ nyin, ati fun gbogbo awọn ti o jina rére, ani gbogbo awọn ti Oluwa Ọlọrun wa ó pè” (Iṣe Awọn Apọsteli 2:39). Awa naa wa lara awọn wọnni ti o “jina rére,” awa naa pẹlu yoo ri agbára Ẹmi Mimọ́ gbà bi a ba le ṣe ohun ti Ọlọrun beere lọwọ wa.

Nigba ti awọn mejila wọnyi gba Ẹmi Mimọ́, wọn fi ède miiran sọrọ, ède ti awọn tikara wọn ko mọ̀ gẹgẹ bi o ti ri fun awọn ọgọfa (120) wọnni ti o fi ède miiran sọrọ ni ọjọ Pẹntekọsti. Eyi jẹ́ ami ti Ọlọrun maa n fi fun olukuluku ẹni ti o ba gba Ẹmi Mimọ́.

Paulu kò gbà pe iṣẹ rẹ̀ ti pari nigba ti awọn eniyan mejila gba Ẹmi Mimọ́. O n wọ sinagọgu lọ sibẹ lati waasu nipa Jesu ki awọn ẹlomiran le gbagbọ́ ki wọn si gba ẹ̀bun Ọlọrun. Ṣugbọn bi o ti maa n ri, nibikibi ti a ba gbe n waasu Ihinrere, awọn miiran kò gbagbọ́, wọn si da wahala silẹ. Paulu mọ pe kò ṣanfaani rara lati maa bá awọn eniyan ti ko fẹ gbagbọ́ jiyan; nitori naa o ko awọn ọmọ-ẹyin rẹ̀, awọn wọnni ti wọn gba ẹ̀kọ́ Jesu gbọ́, wọn si bẹrẹ si ṣe ipade ninu ile-iwe kan nibi ti kò ni si darudapọ ati ariyànjiyàn awọn alaigbagbọ́. Odidi ọdun meji ni o fi wà pẹlu awọn ọmọ-ẹyin wọnyi, titi gbogbo awọn eniyan ti o wà ni ilu ti o wà ni ayika wọn, Ju ati Helleni, fi gbọ́ nipa Jesu Oluwa.

**Iwosan Nipa Agbára Ọlọrun**

Nigba ti Paulu waasu Jesu, ko waasu lori igbala, isọdimimọ́ ati ifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni nikan, ṣugbọn o waasu lori iwosan nipa agbára Ọlọrun pẹlu. Ki i ṣe pe Paulu n waasu rẹ̀ nikan, o gbagbọ́ pe Ọlọrun yoo dahun adura oun nigba ti oun ba gbadura fun awọn eniyan. Ọlọrun ṣe ọpọlọpọ iṣẹ-iyanu nla nitori pe Paulu gbagbọ́.

Akoko yii ni fifi aṣọ ilewọ kékèké ti a ti ta ororo si ti awọn ojiṣẹ Ọlọrun si ti gbadura le lori ranṣẹ fun iwosan alaisan ti bẹrẹ. A fi aṣọ ilewọ kékèké ati ibantẹ́ Paulu ranṣẹ si awọn alaisan ti o wà lọna jinjin rére ati awọn wọnni ti ẹmi aimọ́ n dá lorò pẹlu. Ọlọrun a si wò wọ́n sàn. Ọlọrun n gbọ́ O si n dahun adura igbagbọ́ lọjọ oni fun imularada awọn alaisan, ọ̀pọlọpọ eniyan si ti ri ọwọ iwosan Ọlọrun lara wọn nigba ti wọn ba fi aṣọ ilewọ kékèké ti a ti ta ororo si ti a si gbadura si le ara wọn.

**Awọn ẹmi eṣu gbagbọ́**

Awọn Ju kan wà ni Efesu ti o fẹ le ẹmi èṣu jade lọna adabọwọ ti ara wọn. O fara jọ isin awọn olusin ẹmi-èṣu ti ode-oni. Lẹyin ti wọn ti gbọ́ ti Paulu fi orukọ Jesu le ẹmi èṣu jade, awọn naa dawọ lee lati ṣe bẹẹ pẹlu. Ṣugbọn wọn ko i ti ni idande nipa Ẹjẹ Jesu, nitori naa wọn ko ni ẹtọ lati fi orukọ Jesu ṣe iṣẹ-iyanu. Awọn ẹmi èṣu mọ Jesu. Jakọbu sọ bayi nigba kan wi pe: “Iwọ gbagbọ́ pe Ọlọrun kan ni mbẹ; o dara: awọn ẹmi èṣu pẹlu gbagbọ́, nwọn si wariri” (Jakọbu 2:19). Eyi tayọ igbagbọ́ awọn ẹlomiran.

Ẹmi èṣu ti o wà ninu ọkunrin ti awọn Ju buburu wọnyi n fẹ mu larada wi pe, “Jesu emi mọ̀, Paulu emi si mọ̀ ṣugbọn tali ẹnyin?” Ọkunrin ti o ni ẹmi èṣu na fò mọ́ awọn Ju buburu wọnyi, wọn si sá jade kuro ni ile naa ni ihoho ati ni ifarapa.

Nigba ti awọn eniyan gbọ́ ohun ti o ṣẹlẹ, ẹ̀ru ba wọn, wọn si n fẹ mọ̀ si i nipa Jesu. Ọpọ ninu wọn ni igbalà, wọn si kò awọn iwe iṣe-ajẹ wọn wá, wọn si daná sun wọn loju gbogbo eniyan. Ohun ribiribi

ni fun wọn lati kó awọn oògùn wọn ati awọn nnkan miiran ti wọn n lo ninu isin ẹmi eṣu wọn danu. Wọn ni ero pe wọn ni lati tẹle gbogbo ilana eto ẹsin wọn ki wọn le ẹmi èṣu jinna si wọn, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ eniyan ti o ni igbagbọ́ ninu itan atọwọdọwọ awọn keferi ti n ṣe lọjọ oni. Ṣugbọn Ihinrere Jesu Kristi lagbara ju Satani lọ. Nigbakuugba ti awọn ti n sin Satani ba gboju soke si Jesu pẹlu igbagbọ́, ti wọn ba si jẹ ki O gba ọkàn wọn là, agbára èṣu yoo dofo. Ẹmi èṣu kò ni lagbara lori wọn mọ́, wọn yoo si layọ. Isin ẹmi èṣu ki i fun eniyan layọ, ṣugbọn Ihinrere Jesu Kristi maa n fun ni layọ.

**Ihin Ayọ**

Itumọ Ihinrere ni "ihin ayọ." Nigba ti angẹli nì kede ibi Jesu, o wi pe, "Má bẹ̀ru: sawò o, mo mu ihinrere ayọ̀ nla fun nyin wá, ti yio ṣe ti enia gbogbo" (Luku 2:10). Nigba ti Woli Joẹli n sọ nipa ti igbà Ẹmi Mimọ́, o wi pe, "Má bẹ̀ru, iwọ ilẹ; jẹ ki inu rẹ dùn, ki o si yọ̀" (Joẹli 2:21). Nigba ti Jesu fi itọni lé awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lọwọ, O wi pe, Alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn" (Johannu 13:17).

"Bẹ̃li ọ̀rọ Oluwa si gbilẹ si i gidigidi, o si gbilẹ," labẹ iwaasu Paulu. Nibikibi ti a ba gbe gbé Ọrọ Ọlọrun ga, Ọlọrun yoo ṣiṣẹ igbalà ọkàn. Ọrọ Ọlọrun sọ nipa Jesu wi pe, "Ati emi, bi a ba gbé mi soke kuro li aiye, emi o fà gbogbo enia sọdọ ara mi" (Johannu 12:32).

## AWỌN IBEERE

1 Nibo ni Paulu lọ nigba ti o bẹrẹ irin-ajo rẹ̀ kẹta lati tan Ihinrere kalẹ?

2 Bawo ni o ti pẹ́ tó ni bẹ̀?

3 Awọn ibeere wo ni o beere lọwọ awọn ara Efesu?

4 Ki ni isọdimimọ́ n ṣe fun eniyan?

5 Ki ni a maa n ri gbà lẹyin ti a bá ti gba agbara Ẹmi Mimọ́?

6 Ki ni Jesu ṣeleri fun awọn ẹni ti yoo lọ si gbogbo agbaaye lati lọ waasu Ihinrere?

7 Awọn wo ni Peteru sọ pe a rán Ẹmi Mimọ́ si?

8 Igba meloo ni a ri akọsilẹ ninu Iwe Mimọ́ pe a fi Ẹmi Mimọ́ fun ni lẹyin ọjọ Pẹntekọsti?

9 Ki ni o ṣẹlẹ ni akoko iṣẹ-iranṣẹ Paulu ni Efesu nipa iwosan nipa agbára Ọlọrun ati lile ẹmi èṣu jade?

10 Ki ni ẹmi èṣu naa sọ fun awọn Ju buburu wọnni?